# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1059 MONDAY NOVEMBER 15, 1965 (2D)


20 NOV 65

## Abayọri Ibo

| | |
|---|---|
| A. G. | 35 |
| N.C.N.C. | 7 |
| DẸMỌ | OFO |

# ỌPẸ LỌ NI FẸDIRA



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLOWO

EKO:- Gudugbẹja ! ohunti o sọnu ni Masalasi kọja bata Lemọmu, Lemọmu lo ti nwa bata rẹ ni Mọsalasi, a ṣe Ladani ti o goke lọ pe irun tipoora si ọhun ti ko si le sọkalẹ mọ, nigbayi ni gbogbo awọn janma to mọ wipe, ohunti o sọnu ni Mọsalasi kọja bata Lemomu.

Irohin ko to afojuba ni are, ayẹ yẹ idunnu ati ayọ ti awọn ara Eko ṣe ni oru ijẹta ọjọ Abamẹta ti ise ọjọ kẹtala oṣu yi nigbati Irohin de si etigbọ gbogbo enia wipe ẹgbẹ Afẹnifẹre A. G. lo wọle ninu ibo ti awọn enia na di kọja lọ yi.

Ni ọjọ Abametá na ni awọn enia ilu Eko dibo si n.i ile Igbimọ Asofin Ijọba Ibilẹ Eko. Ṣugbọn nigbati abayọri ibo na jade tan ni deede agogo mẹta oru, ẹgbẹ Afẹnifẹre lo wọle.

Ninu awọn aye mejilelogoji (42) ti nwọn dibo yan awọn Asoju si aye ijoko marundinlogoji (35) ni ẹgbẹ Afẹnifẹre ko ninu aye ijoko na ẹgbẹ Alakukọ si ko aye ijoko meje pere ninu ile Igbimọ na.

Irohin fi ye wa wipe nigbati abayọri ibo na ti jade ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbe na ti bọsi ode ti nwọn si njo kakiri gbogbo igboro ilu Eko awọn enia na si sere titi ti ile ọjọ keji fi mọ kedere.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ti bẹrẹ sọrọ lori abayọri ibo ti o kọja lọ yi.

Ọkan ninu awọn enia ti Oniwe Irohin wa Ejongboro lọ ba ni owurọ ana ni Alhaji A F. Masha, enit/ o ti ise alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko, ninu Ijọba ti o kọja lọ yi.

Alhaji Masha sọ pe, on dupẹ pupọ lọwọ gbogbo awọn enia ilu Eko fun ifẹ ati inurere ti nwọn ni si ẹgbẹ on Afẹnifẹre ti nwọn dibo wọle fun ẹgbẹ na ninu ibo yi.

Alhaji na wa gbadura pe ki Ọlọrun Ọba ti o ni aye ati Orun ki o maa wa pẹlu awọn enia na ninu gbogbo ohunti nwọn ba ndawọlẹ, ki o si maa fi ibukun si iṣẹ wọn.

Awọn enia miran ti n sọ a tun sọ fun oniwe Irohin wa ni ana pe awọn dupẹ lọwọ gbogbo awọn enia ti nwọn dibo wọle fun awọn na ni, Ọgbẹni G. A. Dawodu, Ọgbẹni Hakeem Habib, Ọgbẹni S. A. Jenmi, Alhaji M. I. Onigbanjo ati Ọmọ Ọba Tajadeen Olusi.

Ṣugbọn awọn ohun iyanu mẹji lo ṣẹlẹ nigbati awọn enia na ndibo ni Ọsan ijẹta, Ekini ni wipe Ọkunrin kan lọ dibo ni Ile iwe St Paul, ni opopo Breadfruit, l'Eko

WO OJU EWE KẸFA

# EYI NI ẸDA ỌRỌ TI IKOKU KỌ RANSẸ SI NAIJIRIA

"Ọta ti nbaja ni orisirisi oju ọkan ninu wọn ni ẹgbẹ Olomi omiran ni ẹgbẹ Dẹmọ ẹkẹta ni awọn anikanjopọn ati alalubọ ẹgbẹ oselu ati ẹgbẹ miran to wa ni Middle Belt Ila Orun ati agbedemeji Iwọ Orun oju miran ni ọjọgbọn ti nwọn npe arawọn ni onilu ni ipari ọkẹaimọye ti nwọn nṣe ofofo ti nwọn wa larin wa ti nwọn npe ara wọn ni ọmọ ibilẹ ati ẹgbẹ awọn osiṣẹ.

"Ninu iwe ti mo kọ yi mo pe ara mi ni ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Naijiria ni oruko Asiwaju wa nla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ati ni agbara mi gẹgẹbi akọwe ẹgbẹ Afẹnifẹre,

"Lati ọdun 1962 ti edealyede ti bẹsilẹ orisirisi nkan ni o ti ṣẹlẹ ninu ẹgbẹ wa ọpọlọpọ ninu wa ni o ti gbọn bayi Awọn ohun ti o nṣẹlẹ yi fi han gbangba nipa awọn enia ti o wa ninu ẹgbẹ wa.

Awọn enia wọnyi ti kọ ẹkọ nla eyiti bi enia ṣe ogun ọdun ninu ẹgbẹ oselu kole kọ enia, loni awa [illegible]nu awọn nkan miran ninu iselu ilẹ Naijiria boya o le mu ojulowo iṣẹgun wa tabi iparun, o rọ lori awọn nkan meji.

## ỌNA IṢẸGUN

Ọna kini ni pe, ẹnikan ko kere ninu ẹgbẹ, bi a ba jẹ olotito si aṣiwaju wa, bi a ba tẹle ete ẹgbẹ wa, bi a ba ṣe tan, lati fi ara wa rubọ boba ye, bi a ba wa tun le ni ifaiya ran fun igba diẹ ao ṣẹgun,

Nkan keji ninu ẹgbẹ wa ni ki awọn ọmọ ẹgbẹ setan lati tun ẹgbẹ ṣe ki a si maa sọrọ re tantan, ol o baje ipọnju ati iya ati awọn ohun ibi si ẹgbẹ wa bi a ba le ko ile wa sori apata bi o ba sọ agbara di pupọ ti o siso ara wọn pẹlu awọn enia awọn mẹkunnu ti ki iṣe kiki awọn Ọlọla ati Olowo nikan, bi o ba le fi aye s[illegible] fun eto ẹgbẹ wa lati ma dari re, nitootọ ao ṣẹgun.

Ki ọrọ yi ki o le ye wa da da, a ni lati fe ọrọ meta yi. "Ni ọna kini Tani awọn ọta yi? Lona keji ọna wo ni ao fi ba ọta yi jẹ? Lona kẹta ọna wo ni ao gba lati ma fi ba ija na lọ?

"E jẹki a dahun awọn ibere yi gẹgẹbi ofin awọn osise Irohin ti gba wa ni aiye mọ. Tani ọta yi?

"Gbogbo wa lo mọ ọta yi ẹgbẹ Dẹmọ ni, awọn ẹgbẹ



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

itan na ko ti pari. A ni lati yẹ ọrọ na wo yekeyeke ọna ti nwọn fi jẹ ọta wa, a o si tunyẹ wo bi o ba jẹ pe, awọn nikan ni ọta wa.

"Ọta wa ni Dẹmọ, kiṣe wipe nwọn ya kuro lara wa, nwọn jẹ ọta wa nitoripe ti arawọn nikan ni nwọn mọ, nwọn jẹ ẹgbẹ oselu ti o jẹ ọta ododo, nwọn fẹ sọ arawọn di enia nla ati olowo lara awọn enia, nje ologbon ti o nfẹ ki Ijọba awọn ki o maṣe pari loju nwọn

"Oro ti ẹ wọn logun, anfani ti ara wọn nikan ni nwọn mọ, alafia ẹgbẹrun ọna ẹgbẹrun enia ti nwọn njọba lori ko kan wọn.

"Nwọn pa ara wọn pọ mọ awọn oyinbo onisọwọ ti nwọn si nran arawọn lọwọ, eyiti o ba ti ṣe ti nwọn [illegible] nwọn di ọta ibi iṣẹ.

## ỌTA

Ni ọna kukuru ẹgbẹ Dẹmọ ti di ibi ipade awọn ọta ilẹ Naijiria, nwọn jẹ ohun elo fun ẹgbẹ oselu ni Ipinlẹ Ariwa Naijiria idi ni yi ti nwọn fi jẹ ọta ẹgbẹ Afẹnifẹre, ọta na si ni wọn yio maa jẹ lailai.

Ẹgbẹ Afẹnifẹre nja fun ilọsiwaju orilẹ ede wa isowo laisi da lọwọkọ ominira fun gbogbo enia ati pe ki o mu se pe enia ki i jẹ ẹnikan ko ri jẹ rara.

Awọ isoro t a da ju to niyi I gbara Ọlọrun Orin iṣẹgun yio si gba enu wa ka lẹnu ija yi ọmọ ogun miran yio subu awọn olori ati olo ye miran yio pa ipo da nitiẹ kufẹ ti ara

Ọk n yin yio sọ kiji pe, n o fi ẹnu k n eh n iṣẹgun [illegible]

pe awọn yio pari ija ra, eyiti awọn enia nri iranlọwọ lati ilu miran, awọn ota ati awọn alagba edasi Awọn enia wọnyi ko le wule rara ati pe nitoripe nwọn ko le se ju pe, ki nwọn jẹ ero ẹhin lori iṣẹgun yi.

"Nwọn lo le iṣẹ opomulero fun iṣẹgun yi sugbọn bi a ba nri agbara wa to yege larin awọn ọmọ ẹgbẹ wa ti awọn ajẹgẹpọ ọmọ ẹgbẹ wa si muna doko, iṣẹgun wa duro gbọnin gbọnin

"Ti a ba ti ọna wa ti o mọ rokoso larin awọn iyọnu iṣẹgun yi. Nitoripe awọn nkan ti a nri yi yio fi pe agbaiye enia nṣe tiwa.

"Ọna miran ti o ye ki a fi sọkan ningbagbogbo ni wipe ki iṣe Dẹmọ nikan ni ọta wa, paapa kọ se ọta ọrun ti o gbọ ẹbọ ti o wa lẹhin Dẹmọ ti nwọn nhu iwa ipa ẹlu ijọba onikumọ to wa ni Ariwa Naijiria nikan tun ni ọta wa pẹlu

Awọn agbara okunkun yi ngba awọn anfani awọn bi enile ati awọn onisowo nla nla to wa ni ipinlẹ Ariwa silẹ awọn agbara okun yi ni awọn Oyinbo Gẹẹsi Ẹgbẹ oselu nwọn ni ẹgbẹ Ol mi eyi ni ẹgbẹ oselu onikumọ awọn ẹgbẹ onisowo nlanla darapọmọ awọn alejo oniso wo kiṣe awọn ẹgbẹ Dẹmọ tasi loni agbara

Ẹgbẹ Demọ to wa ni Iwọ orun Naijiria je ohun elo fun iwa tulasi ati awọn oowo Bi a ba gbagbe awọn wonyi wa ni ipinle miran

Ki a ra ti Dokita, Dokita Okezie ti da ẹgbẹ ti nwọn si tun ri Harold Biriye ati awọn ẹgbẹ Olomi wewe we ti o wa ni Middle Belt ti nwọn nje ara won ni ọ bo ibile ati ipinle Agbedemeji Iwọ Orun to wa lowo Okotie-Eboh ati Osigie.

Awọn ti o wa ninu ọkọ e be ni ni awọn ọgọ awọn Ṣoja ati ọ ọpa eyiti o fi ile Naijiria si abẹ awọn ajoji ti nwọn si tun npaṣẹ pelu Kini o fa? Nitoripe awọn ile ifowopamọ wọn, ẹgbẹ onisowo, awọn ti o nya wọn lowo kole, ṣe agbẹ ati ti agbagba ni gbigbin, ẹgbẹ

WO OJU EWE KARUN

# Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

## ENIA ILU EKO EWO LẸ ṢE ?

Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oyelati kesi awon Adibo ilu Eko lati lọ sora nipe awon enia ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nwọn so pe nwon ko fi ara mo ẹgbẹ kankan ti yio gbe apoti ibo silẹ awon ti a npe ni "Indendent AG"

Mo si bẹ gbogbo ẹnyin ti yio dibo ni ilu Eko lati kọ awon ẹgbẹ onijibiti yi silẹ nitoripe nwọn ki iṣe ẹgbẹ Afẹnifẹre bi koṣe wipe ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ni nwọn iṣe ati pe ti nwọn ba le dibo fun won wọle ẹgbẹ Dẹmo ni nwọn yio faramọ.

Nitori eyi ẹnyin Adibo ninu idibo si ile igbimọ Amofin ijoba ibilẹ ilu Eko to mbọ yi ẹ maṣe dibo fun ẹgbẹ miran jn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre Olotu mo dupẹ fun aye ti e gba mi

Emi ni
K. A Owanja
EKO

## Ofin Yi Ko Dara

Olotu jowo gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ogbon ati oye lati kesi Ijoba ibilẹ ilu Ibadan ati Ijoba ibilẹ ẹkun Oshun lori awon iwe irohin ti awon Igbimo Ijo'a ibilẹ na ṣe alaye ofin pe ko gbodo de ilu Ibadan ati ni ẹkun Oshun eyiti o jẹ wipe o ya awa enia ilu na lẹnu nitori pe awa enia ilu na koso pe ako ka awon iwe irohin na

Eyi ti o jẹ ohun pataki ti o tun jẹ ohun ti anbẹ Ijoba ibilẹ ilu Ibadan ati ti ẹkun Ohun ni pe ako fẹ duro laijẹ wipe a nr iwe irohin Imolẹ eyiti o jẹ iwe ti ko fi ara mo egbe oṣelu ati ohun ti iwe Irohin Imole ri o so osi kọn fun otito ati ododo

Inu awa onkawe Irohin Imole ni ilu Ibadan ati ẹku Oshun yio dun bi awon Igbimo to ṣe ofin yi ba le fi ofin na sile ati pe ki nwon jẹki ama ri awon iwe irohin na ka tabi ki a ri mara ni ilu ti nwon ti ṣe ofin na.

Emi ni
Kunle Adeọla
Ibadan

## Akoko Ofin Pajawiri Ti To

Olotu Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ogbọn ati oye lati kesi Alakoso apapọ Ijọba Naijiria ati adele olori ilẹ Naijiria lati tete inu oju to rogbodiyan to nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Ọrun Naijiria bayi ki nwọn tete ṣe eto lati ṣe ofin pajawiri si Ipinlẹ na.

Mo ro pe o yẹ ki awon Olori ilẹ wa meji yi ro ranti pe ko ti si iru nhu ti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun yi ninu ọdun 1962 nigbati awọn ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ na fi ju aga lu arawọn ti ija kankan ko ṣẹlẹ ju eyi lọ ti apapọ Ijọba fi gbe ofin pajawiri de Ipinle Iwọ Orun.

Asiko ti to bayi lati tete ṣe eto ofin pajawiri si Ipinlẹ na ki ohun ti o nṣẹlẹ yi le lọ silẹ ju bi o ti ṣe wa yi lọ. Mo ro pe awọn apapọ ijọba fẹ fi eyi ṣe ikilọ ti nwọn ko ṣe ṣe ofin pajawiri si Ipinlẹ na ati pe ki gbogbo ohun ti o nṣẹlẹ na le lọ silẹ.

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ajinde yio ma jẹ o.

Emi ni
Jọkẹ Aassan
EKO

## Ilu Akinmorin Nfẹ Ile Iwosan Nla

Olotu jowo gba mi laye diẹ ninu iwe nyin to nta ti akọra gbigbona lati kesi Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria lati iun awa enia ilu Akinmorin ni ile iwọsan nla eyiti awọn laisan ati ibiti awon ti o ba fẹ bimọ yio ti lọ ma bimọ.

Ọpọlọpọ awọn enia ilu na lo jẹ wipe o ma nsoro fun lati lọ si ile iwosan lati lọ gba agun ti ara wọn ko bh da to fi jẹ wipe ibiti awọn enia na yio ti lọ gba ogun ti ara wọn ko ba enia si ti jinna pupọ ati pe eleyi si ngmu ọpọlọpọ iku lowọ fun awon enia ilu na

Inu awa enia ilu na yio dun bi Ijọba Ipinlẹ Iwa Orun Naijiria ba le se iranlowo fun awa enia ilu na ki nwọn si tete fun wa ni ile iwosan nla yi ati awon nkan miran bi na mọnamọna, Ẹrọ omi ati awon ohun idagbasoke miran.

Olotu ẹ ṣe pupọ fun aye ti ẹ gba mi ajinde yio ma jẹ o.

Emi ni
F. Adeoye
Akinmorin


## Iwo Ha Nfẹ Ile L'Eko Bi

| | |
|---|---|
| Room | £3 |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room / Parlour | £6 |
| Room / Shop | £15 |
| Flat (Lagos) | £20 |
| Flat (E.B) | £25 |

Ti o ba nfẹ ọkan ninu awọn ile wonyi yara tete lọ ri Ọgbẹni ODUS— 178 Bamgboṣe Street Lagos. ni deede agogo mẹrin i ole si agogo mẹfa irọlẹ ijafara lewu anfani nla kan ni eyi jẹ fun ọ pe o ri ile l'Eko



# Kere o Kere o Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo han-nhanon Egbogi LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pelu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ka k Ile Naijiria

A wa na njẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan ọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ojọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi owọ sọya ta'i pe ile ati fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, Igbẹ sise, ako ri igbo nsẹ deede, inurirun nigba kugba ara wiwo, Ẹsanro ehin didun sisan ati aika tiran kedere ko doro buruku lara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbi pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn nba lo egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ejẹ se lara enia nipa sisi di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile mẹfa abo (6/6 pere Igo kekere ṣile mẹta abo (3/6) pere. Ber Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ n Ṣọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

# ỌKUNRIN KAN GBA IDAJỌ IKU !

ABEOKUTA:- Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi ni adajọ agba ile ẹjọ giga ti ilu Abẹokuta ti paṣẹ pe ki nwọn lọ yẹ igi mọ ọkunrin Dirẹba kan Oluwọle Fatoyinbo lẹṣẹ lori ẹsun pe ọdaran ọkunrin na pa obinrin kan.

Gẹgẹbi ọrọ ọlọpa to ba ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye pe ni ọjọ kẹtadinlọgun oṣu kẹjọ ẹdun to kọja lọ yi ni obinrin kan Wulemọtu Fashọla ti ngbe ni ilu kan ti a npe ni Ararọmi Ibeshe lẹba Ilaro lọ si abuleko kan ti ko jina si ilu wọn ati pe ko si mọ pe ọjọ na ni ọjọ iku o si to.

Ọlọpa na tun ṣe alaye pe gẹgẹbi obinrin na ti nlọ lọju ọna to lọ si abuleko na ni ọkunrin ọdaran yi Oluwọle ba jade lati inu igbo nibiti o lọ fi ara pamọ si eyiti o je pe o ṣa obinrin na lada pa patapata.

Ọlọpa to ba ọdaran na ṣẹjọ tun ṣe alaye fun ile ẹjọ na pe gẹgẹbi obinrin na ti ṣubu lulẹ lori ada ti ọkunrin a ti ṣa ni okunrin na ba joko le obinrin na lori to tun bẹrẹsi ni ṣa lada mo ibiti o ṣubu si.

Ọlọpa to ba ọdaran na ṣẹjọ tun ṣe alaye pe nigbati awọn enia to ti kọja loju ọna na ni Faloyinbo ti o ti fi ada ṣa o ... na ti o tun oko le oku obinrin na lori ni awọn enia to fẹ kọja loju ọna na ba kegbe eyiti o fi jẹ wipe ọkunrin ọdaran na si salọ pẹlu ada lọwọ rẹ.

Lẹsẹkẹsẹ ti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ ni awọn ọlọpa ti bẹ ẹsi ni wa ọdọ-an na kakiri eyiti o fi jẹ wipe awọn ọlọpa si ri ọkunrin na mu ti nwọn si mu lọ si teṣan wọn lati lọ ti mọle.

Ninu idajọ Adajọ agba ile ẹjọ na ni ọgbẹni Charles Madarikan ti ṣe alaye pe gbogbo ọrọ ti ọlọpa to ba ọpasau na ṣẹjọ sọ niwaju ile ẹjọ giga ni on si gba gbọ atipe otitọ ni a fọ ọrọ ti ọlọpa tabi awọn ẹleri sọ niwaju on.

Ọgbẹni Madarikan tun ṣe alaye pe on ko gba gbogbo ọrọ ti ọdaran na sọ niwaju gbọ bikoṣe wipe iro patapata ni gbogbo ọrọ ọdaran na.

Adajọ ile ẹjọ na si paṣẹ pe ki nwọn lọ yẹ igi mọ ọdaran ọkunrin na lẹṣẹ.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Awọn ẹnkan yio ṣe iranlọwọ fun ọ nipa ohun ti o nfẹ idina fun ọ ninu ohun ti o ngba lere ninu ọkan nṣe ni ki o mura giri ma ṣe tura silẹ.

PISCES (Feb 21 May 20) Maṣe jẹki aarẹ mu ọ rara loni bi yio ba di iwaju ọla, nṣe ni gbogbo rẹ yio ti lọ si po, ko si spoiti yio le ba tirẹ jẹ.

ARIES (May 21 April 20) Ọjọ oni dara lati lọ ṣe abẹwo awọn ọrẹ rẹ, ki o ṣe ma ṣe adinwo nipa ohunti o nro ni ọkan rẹ.

TAURUS (April 21 May 20) Maṣe gba ohun kan ti o npa ọ laiye si otitọ ṣugbọn ṣa se suru, frawọ rẹ mbọ wa tan na rẹ iba ọjọ iẹ li o ku, alafia ni fuu ọ, ati fuu ile rẹ.

GEMINI (May 21 June 21) Agbara iṣẹ ṣiṣe si mbọ li ọkan rẹ lati ṣe nṣe nj ki o tu ara rẹ di ni a ure ki ki o ma ba fi iṣẹ ṣiṣe pa ara rẹ lori.

CANCER (June 22 July 22) Maṣe ni ero buburu kan si iyawo nṣe ni ki o wa irẹpọ pẹlu rẹ. awọn ẹgbẹ rẹ li o da ede ko yede na silẹ larin iwọ pẹlu rẹ.

LEO (July 23-Aug 22 Ọjọ oni li o dara ki gbogbo ọrọ rẹ yori si rere, nse ni ki o dupẹ lọwọ ọjọ rere bi ti oni yi

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Arẹ fẹ ma ọ, nse ni ki o din gbogbo s; ati wahala rẹ ti oni ku m se lero wipe ọrẹ re ... yio ... a ọ lọwọ

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Bi o ba ṣe da a ... ra lo ni, iwọ yio se orire, ... atijọ kan tio ti ... yio j ... ki o si lo ọpọlọpọ nipa ọrọ ara rẹ

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Iwọ ṣe longẹ re lọpọlọpọ iwọ yio si tun gba alejo pupọ pẹlu, m ṣe t n l ... ese ko rẹ damn m lori ọrọ ti ko nilari, se oh ... ti o fẹ ṣe, yio si dara fun ọ

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) ... ni ni ... siko ti iṣẹ yio wa si ara rẹ lati ṣe Sugbọn amod ko fun ... la e, ki o ma si ṣe jẹki eyiti o ti ṣe silẹ ki o bajẹ

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Tete mara si awọn iṣẹ ti o ba wa nilẹ la se iwọ yio gbọ ironi ... iṣẹ kan ... ase ko iyekiye ti nwọn ba fẹ san fun iṣẹ na ki o s wo ṣe fun wọn


## Ha! Kini Ẹleyi O




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three elephant Brand mosquito coils dara pupọ, A ni o dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ, Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati iden.

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three elephant Brand coils tire loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi yio ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki ori daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu fun ọ

Three elephant Mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ti ile itaja kakiri orilẹ ede yi.

*DISTRIBUTOR*

**Amos GBENLE & BROTHERS**

34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

PHILIPS
for
RADIO
PHILIPS

# Eyi Ni Eda Oro Ti Ikoku Ko

## Lati Oju Ewe Keji

ti o nmojuto a nlọ a nbọ ọkọ oju omi, asoju egbẹ idabobo ati bẹẹbẹẹ lọ nsagbara lati sọ awọn ohun al m,ni wa di ti wọn.

"Bi ẹba k yesi ohun ti o fa a rijẹ airimu a risẹse larin wa loni owo osu ranpẹ aini ẹkọ ati ogun to, awọn arun ti ojẹ aimọkan ati bẹẹbẹ lọ ẹo ri gbogbo ohun ti ofa la ri awọn Oyinbo to wa ni ilẹ wa.

"Ati ni arin awọn Oyinbo yi nwọn fẹ ki ile Naijira je aabo fun ar..w n ni won fi nse iṣẹ k.ja a coko lati ri pe nwọn pa iwa omin ra ti ilu wa re ati .wọ i tio fe tun ile wa se lori ojulowo ominira kuro loko e r u Oyinbo ni nwon ti bi subu.

"Lati igba ti awọn ti nja fun ilẹ wa je, nwọn kole d. se rara laijẹ pe nwọn ni aṣoju ni nwọn yio maa ko ati pe nwọn yio si wa lẹhin daada. Nwon ni ilo awon enia ati ẹgbẹ yio ṣe iṣẹ buburu yi fun wọn, ey ti ere rẹ fun wọn yio je owo, ipo nla, fifun ni iṣe agbase to mu obi lowo.

"Ni ilẹ wa loni, awọn ti o jẹ as'w ju n nu iṣẹ buruku na ni ẹgbẹ Olomi ati Dẹmọ. Awon Oyinbo yi nio opolopo ẹgbẹ kekeke orisi.isi ẹgbẹ awọn Oṣiṣẹ, awon ti o yonda ara nwon pẹlu awon oluko ti Unifasiti awọn ti nwa imo ijinlẹ paapa awon enia to npe ara wọn ni Ijọ Ọlorun.

"Nitorina ota ti a nbaja ni okan kojọkan Ijoja ninu won ni ẹgbẹ Oloni, Dẹmo, aw n m ran ni ẹgbẹ oṣela to wa ni Middle Bel, Ipin lẹ Ila Orun ati agbedemeji Iwo Oran ati awon miran ni awon omo Naijiria ti nwon nba awon a eto onṣowo finu konu ati awon kan ti o wa n nu ẹgbẹ oṣiṣe kan ti o nje ICFIU pelu.

"Ati awon orisirisi ọjọgbọn to wa ni awọn Yunifasiti pẹlu awọn ẹgbẹ oni sowo kan to wa ni ilẹ Naijiria ti awọn Ijọba wa wa lẹhin wọn.

IYOKU DI ỌLA ]


## APIAS RHUEMATIC & DRAGES

Jẹ ojulowo hanunhanun egbogi Jamani to lagbara gidigi di fun Iwosan "LAKUREGBE" to nba enia ja

Oriṣiriṣi lakuregbe ni o wa Lakuregbe Arungun ti o ma nsan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o ma nwu enia ni ẹsẹ roboto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o ngbẹ erikerike danwo kori bi o ti rorun lati lo tabi ki o ma ṣe ayipada ẹsẹ, ara tita bi eyiti enia fi ata obẹ pa ibadi obi egusi ori wiwo, ako iba abi p pon tabi riron.

Bi enia ko ba gbajumo lati toju rẹ lasiko o le so owo pa enia



ATI NI ṢỌBU

IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN


# O Ti De Jaburata

Eyi ni lati kede fun awọn Onibara wa pe Iwe Itumo Ala, Iṣẹ Wiwo, ọjọ ibi Ọmọ de lati Oogun Ajẹbidan alapapo wa nilẹ fun tita nisisiyi, tete wa ra irẹ loni ki o to tan

A s i tun ṣ;ṣ; ṣe Iwe Itumo Ala miran ati owo Joseph Alala

Irohin ko to afojuba 3/6d peni ni, ẹyọ kan, mejila tabi dosin ni rẹ jẹ 30/-

J. O. SHOYINKA
P. O. Box 159,
tabi 9, Iyala Street.
Mushin.

A s i nfẹ awon ti yio ma ba wa ta awon iwe wa na

Tete wa si ọdọ Olotu



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

POPULAR PRINTING PRESS
9, Iyala Street, Mushin


## The NEW HOOVER

Washing Machine Makes Clothes Whiter and Brighter

It's easier the....

**HOOVER** way

The NEW HOOVEMATIC washes rinses spins dry 6lbs. of clothes in 4 minutes all in one continuous operation. That's the amazing performance of the new Hoovermatic, a combined Washing Machine and Spin Dryer.



AVAILABLE AT

LEVENTIS TECHNICAL

MARINA — IDDO — IBADAN — KADUNA — JOS — KANO — P. HARCOURT — ABA

and Kingsway Stores


**E Ma Ka Iwe Irohin Imole Lojojumọ**

# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA*

No 1,503 MONDAY NOVEMBER 15, 1965 (2)

## Ẹgbẹ Afẹnifẹre Yo Enia Mẹtala Kuro L'Ẹgbẹ

EKO:- Ni opin ọsẹ to koja lọ yi ni irohin de ile iṣẹ wa lati ọwọ awọn omo egbe Afenifere ni ilu Eko, Alhaji A. F. Masha fi owo si ni nwon ti se ivede pe egbe Afenifere metala ti gbe apoti ibo silẹ pe awọn yo tun je Alatako si awọn omo egbe ti ẹgbẹ Afenifere mu sile ni egbe na ti yo kuro l'egbe.

Awon omo egbe Afenifere metala ti nwon yo kuro ninu egbe na lati ejo korun ẹsu yi ni Ogbeni Badmus Agoro ti Ward A1, Raisaki Yusuf Ward A4, Fatai Bis h Ward B4, Afolabi Ishola Ward C4, A. Awodeinde Ware D1, S. Odon Ward E1, A. Ogidan Ward F3, B. O. Sunmonu Ward G1, R.O. Khalidson Ward H2, H. O. Idris Ward H3, J. B. Olorunkoya Ward H5 ati Ogbeni M. A. Ogungbadero Ward H 6,

Awon omo egbe Afenifere tun ṣe alaye pe ki enia kankan maṣe dibo fun awọn enia na.

# ỌKUNRIN KAN TA ỌMỌ RẸ NI EDEGBETA PONUN

IBADAN:- Gbogbo enia to wa ninu ile ẹjọ gantan ti ilu Ibadan lo yanu silẹ ti nwọn ko le pade nigbati Ọgbẹni Ganiyu Iṣhọla ti o jẹ ẹlẹri nsọ fun ile ẹjọ na pe ni oṣu keji ọdun to kọja lọ yi ni Tijani Ọlayiwola wa sọ fun on pe ki Ishọla ba on wa enia to le ra ọmọ on Ọkunrin ati pe on fẹ ta ọmọ na.

Ọgbẹni Ishọla tun ṣe alaye pe on sọ fun ọrẹ on Tijani Ọlayiwọla pe ki o maṣe ta ọmọ rẹ gẹgẹbi ẹru ati pe Ọkunrin Ọdaran na ko si gba fun on lẹnu ati pe o si ta ọmọ rẹ na ni ẹdẹgbẹta ponun (£500) fun onisowo kan.

Ọgbẹni Ganiyu Ishọla tun ṣe alaye fun ile ẹjọ pe Ọkunrin na si ta ọmọ rẹ Latifu fun Ọkunrin kan ti nwọn npe ni Usman Dangogo ni ẹdẹgbẹta ponun (£500) ni adugbo kan ti nwọn npe ni Oke Shapati, Ibadan.

Ọgbẹni Ishọla ti o jẹ ọrẹ Ọlayiwọl tun se alaye fun ile ẹjọ gantan pe nigbati ọdaran na ko gba fun on lẹnu ni on ba lọ fi oran na sun ni Tesan awọn Ọlọpa pẹlu ọrẹ on lori pe odaran na fẹ ta ọmọ rẹ gẹgẹbi ẹru.

Ọgbeni Ishola tun ṣe alaye pe ọrẹ on Ọlayiwọl atun ṣe alaye fun ọmọ rẹ to fẹ ta ni ẹdẹgbẹta ponun (£500 ti nwọn npe ni Latifu pe on fẹ mu on fun Ọkunrin kan lati lọ ma gbe lọdọ rẹ ati pe o si ma ko iṣẹ ọwọ lọdọ Ọkunrin na.

Fi ọjọ ti Ọdaran Ọlayiwọla ta ọmọ rẹ Ọkunrin Latifu ni ẹdẹgbẹta ponun (£500) fun Ọkunrin Onisowo na ni awọn Ọlọpa ba lọ mu ninu ile rẹ.

Nigbati Agbẹjọro fun Odaran na Ọgbẹn O. Akande bere ọrọ lọwọ Ọgbẹni Ishola pe nje iwọ ko lọ gba ọrẹ rẹ ni imọran pe ki ọmọ rẹ lọ kọ iṣẹ ọwọ? Ṣugbọn Ọgbẹni Ishola tun dahun pe on gba Ọlayiwọla ni imọran lati jẹ ki ọmọ rẹ lọ kọ iṣẹ.

Ile ẹjọ gantan ti sun igbẹjọ na siwaju, Bi nwọn ba ti ṣe ẹjọ na si ẹ a ma gbo.

Bakanna ni irohin to tun ti ye wa pe Ọkunrin kan Funsho Asolo ti ile ẹjọ ti Ijọba Ibilẹ ti ilu Ogbomọsho ti kan Ọkunrin Ọdaran na pe o ji ọmọ gbe ni a gbọ wi pe ile ẹjọ na ni o ma lọ ni ay... ati alafia ati pe ko ni ... kankan lati jẹ niwaju ile ẹjọ na.

Ninu ọrọ olopa to Ọkunrin na ṣe ... ni o ti ṣe alaye pe okunrin na ji Onild... Ari... Ade Ad. kẹ gbe ni ile awọn obi rẹ lati lọ fi ṣe iya wọ... ẹyiti ile ẹjọ na ṣe alaye pe ko jẹbi esun na.

## Akiyesi

Eyi ni lati fi ye ẹyin onkawe Irohin Imọlẹ pe ẹ un ọrọ Ler Rogbodiyan ẹgbẹ Afẹnifẹre lati ẹnu akọwe Agba ẹgbẹ na Ọgbẹni S. C. Ikoka ti o wa ni Ghana nisisiyi ti bẹrẹsi jade ninu iwe wa lati oni lọ, ẹ wo oju ewe keji.

Tete yara lọ ra iwe Irohin Imọlẹ tirẹ loni ki o si ka ọrọ na Oyinmọmọ na.

## OPẸ LO NI FẸDIRA

### LATI OJU EWE KINI

Nigbati Ọkunrin na wọle lọ lati lọ dibo, ko tete jade, ni awọn Ọlọpa ati akọwe ibo ti o wa nibẹ ba fun'ra si Ọkunrin na, ṣugbọn nigbati o jade ti awọn Ọlọpa si bere ohun ti o nse ninu ile, Ọkunrin na ko le sọrọ, bi o si ti wo'oju Ọlọpa ni gbogbo ara rẹ ba ngbọn tití, nigbati nwọn wo apo rẹ, nwọn ba iwe ibo kan nibẹ ni nwọn ba wọle ibo lọ.

Ọkunrin na ti da Omi-Oloro sinu apere ibo Alhaji Masha awọn iwe ibo ni a ri ti o ti bajẹ. Ni awọn Ọlọpa ba mu lọ si Tesan. A si lero pe yio farahan niwaju adajọni owurọ yi lati sọ ti ẹnu rẹ.

Onirura awọn enia ni nwọn ti nkọwe ... si Alhaji Masha fun ipadabọ ti ẹgbẹ rẹ tun pada si Ori aga akoso Ijọba Ibilẹ Eko.

Ọkan ninu awọn enia na ni Oloye Adeniran Ogunsanya ẹniti ṣe Alaga Igbimo Amuṣẹṣẹ ẹgbẹ Alakuko ni Eko.

Oloye na ṣe alaye ninu ọrọ rẹ pe, "Lati ọjọ ti awọn enia ilu Eko ti ndibo, nwọn ko ti di o bayi ti wọle fun ẹgbẹ Oṣelu kan ni Eko.



ALHAJI M. L. ONIGBANJO

Asoju Egbe Afenifere ti o wole ni Ward A4

Printed & Published by Modupe Printing Press, 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45 Campbell Street Lagos. 15/11/65